# Awon adiye ninu oko osin adiye



# *Awon* adiye *ninu oko* osin adiye



Oko osin adiye je ayika ti o wuni, agbe olosin adiye ma n moju to oko re, o si ma n fun won ni itoju ti o ye lati ri wipe awon adiye oun wa ni pipe laikose alaini ohunkohun.

Idi pataki meji ni agbe aladiye se nfi ife han bayi si awon adiye.

- Agbe aladiye n se itoju awon adiye re, paapa awon ti won n ye eyin, nitori won npa owo wa si apo agbe.
- Ati nitori lati ta awon adiye na fun awon eniyan ti yoo pa won fun jije.

Ati idi kini ati ikeji, kosi eyi ti fifi ife han yi je anfani kankan fun awon adiye. Fifi ife han yi wa fun igba die ni, logan ti awon adiye ti won

n ye eyin ko ba ti ye eyin ti o joju mo, won yoo di tita fun awon eniyan ti yoo pa won je.

Owe Yoruba kan so wipe “Ife ti a fe adiye ko denu, ibi k'apa je lo mo.” Ni igbakigba ti agbe ba fe se ore tabi ti molebi re ni alejo, nse ni yoo wo inu ago adiye re ti yoo si mu eyikeyi ninu awon adiye na.

Ile aye yii dabi oko osin adiye ti esu si je agbe olosin adiye. Jesu Kristi, Olugbala wa pe esu ni omo alade aye yi - eni buburu.

*Ole ki i wa bikose lati jale, ati lati pa, ati lati parun, Emi wa ki won le ni iye, ani ki won le nii lopolopo* (**Johanu 10:10**)

Satani le farahan bi "Angeli imole", bi eni ti o nbikita, sugbon "eletan" ni. Ilepa re ni lati jale, ati lati pa, ati lati parun!

Iwo na le gba etan gegebi Adamu ati Efa se gba etan ninu ogba Edeni, ti o nro wipe ohun rere kan wa fun o ninu aye, ti o nro wipe nitooto ni aye feran re tabi ti won bikita fun o.

Ranti pe, Satani wa si odo Efa bi aladugbo ti oni ife re. O wa ni aworan Ejo, ti o je okan ninu awon alajogbe ogba na. o se ileri fun won wipe won yoo dabi Olorun, ati wipe won koni ku gegebi Olorun se so wipe won ma ku. "E je eso na ki e gbadun emi yin".

**Genesisi 3:4-5**

*"Eyin ki yoo ku iku kiku kan", Ejo ni o so bee fun Obirin na. "Nitori Olorun mo pe, ni ojo ti eyin ba je ninu re, nigbana ni oju yin yoo la, eyin yoo si dabi Olorun, e o mo rere ati buburu.*

Iwo sa ru ofin Olorun, ijiya kosi fun o, nse ni o maa di oloro sii, Iwo yoo di eniyan pataki lawujo. Aye re yoo yi pada si rere lojiji! Satani nfun o ni awon idaniloju daradara wonyi.

Iro nla nio. Logan ti iwo ba ti ru ofin Olorun ni Satani yoo fi o sile fun ijiya ese re gege bi o ti se fun Adamu ati Efa. Iwo nikan ni o ma je iya ese re.

Ona yi ni Satani n gba lati maa se isakoso ati idari eto aye re.

Enikeni ti o wu ki o je, boya ise re ntesiwaju tabi beko, tabi oga ile ise nla ni o; Oloye nio lawujo, akowe, omo eyin oko, tabi awako nio ati bebelo; Enikeni ti ko ba I tii di ominira kuro lowo Satani, je Adiye ninu ogba re.

*“Emi ni ilekun: bi enikan ba ba odo mi wole, oun ni a o gba la, yoo wole, yoo si jade, yoo si ri koriko. Ole kii wa bikose lati jale, ati lati pa, ati lati parun: emi wa ki won le ni iye, ani ki won le nii lopolopo.*

*Emi ni oluso-agutan rere: oluso-agutan rere fi emi re lele nitori awon agutan.”*
**(Johanu 10:9-11)**

Ni iyato si Satani alarekereke, ti o n gba emi eniyan bi o se wu u fun anfaani ara re, nse ni Jesu fi emi tire lele fun anfaani wa, nitori oun ni Oluso aguntan rere. Jesu ti san idiyele fun ominira wa kuro ninu ago osin adiye Esu.



Sugbon iwo ni lati moomo lo anfaani ise ore ofe ti Jesu pese fun o lati jade kuro ninu ago Satani.

Fun gbogbop ojo kookan ti o nlo lori ile aye yi laiko gba ipese ti Jesu ti se fun ominira re, nse ni o fi ara re sile ninu ewu de ojo ti won yoo pa o je bi adiye.

Oni ni ojo itewogba fun igbala re ki iwo na le so bi Jesu ti so ninu Iwe **Johanu 14:30**, *"... nitori alade aye yi wa, ko si ni nkankan lodo mi."*

Lati gba ise ominira yi rorun pupo. Rirorun ti o rorun yi ni o mu ki o ru awon ologbon aye yi loju.

Gba adura ijewo yii.



*"Jesu Oluwa, mo gba lati gba ise ominira re loni, mo wa si odo re pelu okan mi, gba mi gege bi omo re, wemi mo kuro ninu gbogbo ese mi ti o ti fi mi sinu igbekun satani, tu mi sile loni ki o si di Oluwa ati Olugbala mi. Mo yonda okan mi fun o. Fun mi ni agbara lati di omo re loni. Mo dupe pe O gba mi. Jesu o seun ti O di Oluwa ati Olugbala mi loni."*

Ti o ba ti gba Jesu Kristi gege bii Oluwa ati Olugbala re, tabi o n fe oro iyanju siwaju sii. Jowo te atejise si:

*ehcnigeria1@gmail.com*

Mo fe lati gbadura fun o, ki nsi ki o ku oriire fun ominira re kuro ninu ago Satani





Ti o ba fe iwe pelebe yii si jowo kan si
https://www.ehcnigeria.org/bible-courses/


Every Home

**Every Home for Christ Nigeria**

7, Adekunle Akala St., Off Fatai Irawo St., Ajao Estate, By International Airport Road, Lagos

+234 (1) 293 2331 | +234 (0) 815 5501 000
+234 - 815 550 2000

info@ehcnigeria.org | www.ehcnigeria.org